


# Irohin Yoruba

No. 766 FEBRUARY 10 — FEBRUARY 16, 1960 Kobo Meji (2D.)

**LAKAYE ORO.**

OJU Oluwa mbe lara awon olododo, eti Re si si si igbe won.
Oju Oluwa kan si awon ti nse buburu lati ke iranti won kuro lori ile.
Awon olododo nke Oluwa si gbo, o si yo won jade kuro ninu ise won gbogbo.

# IJOBA IWO-ORUN YIO NA £14,000,000 LORI IṢẸ AGBẸ

## Pakute mu ẹniti o nsa fun olowo ori

IJẸBU-ODE.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni Adajọ Kotu Ibilẹ Ijẹbu-Ode kan kilọ fun ọdaran kan, Nọsiru Adẹbambọ, ẹniti nwọn mu wa si Kotu na pe ko san owo-ori rẹ, pe on fi eyi fa a leti pe ki o tete san owo-ori na lalpe yi.

Awọn ọlọpa ni, bi ọdaran yi ti ri awọn akọwe olowo-ori ni abule Ẹgbẹ ni o ba kanlugbo ti o si tẹsẹ bọ pakute ti nwọn kẹsilẹ fun ẹranko, o sa agbara titi, ẹsẹ rẹ ko ṣe yọ, nibiti o gbe nkegbe ni awọn olowo-ori na ba wọ igbẹ tọ ọ ki nwọn to dasilẹ.

ILESHA.

NIGBATI awọn Ẹgbẹ Agbẹ Ifẹ ati Ilesha nṣe ipade Ajọdun Ifihan ohun-ọgbin ninu Gbọngan Apejọ Ile Ẹkọ Giga "Ilesha Grammar School" ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni Oloye Akin. Dẹkọ, Minista Alamojuto Eto Iṣẹ Agbẹ ati Ohun Isun Ilẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun sọ ninu ipade na pe apapọ owo ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun yio na lori Iṣẹ Agbẹ nikan fun eto inawo ọdun marun ti o mbọ yio to ẹdẹgbẹrin-ọkẹ ponun ((£14,000,000).

Oloye Dẹkọ tun ṣe alaye siwaju pe, ọdun 1960 yi yio jẹ ọdun alarisiki pupọ, ki iṣe fun Apapọ Ijọba Naijiria nikan ṣugbọn fun Ipinlẹ Iwọ-Orun paapa pẹlu, nitori o jẹ ibẹrẹ Iṣẹ Idagbasoke -ilu ọdun marun pataki ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun fi igboiya dawọle fun Eto Idagbasoke Iṣẹ Agbẹ. O ni Ijọba fura si i pe ire-oko ati awọn ohun-ọsin jẹ nkan agbẹ pataki, ilọsiwaju wọn si nfẹ amojuto gidigidi.

Oloye na tun sọ fun ipade na pe, awọn ẹlẹkọ-ijinlẹ lati ilu Israeli ti de si Ipinlẹ na, nwọn si ti bẹrẹsi mojuto iṣoro iṣẹ agbẹ wa" lati le gba Ijọba ni imọran lori idagbasoke iṣẹ agbẹ. Nipa ọgbin koko, Minista na sọ pe Ijọba on yio mura si eto pinpin awọn oriṣiriṣi eso koko ti o nyara dagba fun lilẹ, o si fi kun ọrọ rẹ pe, on ni ireti pe, awọn yio ma a le to ẹẹdẹgbẹta ọkẹ eso-koko lilẹ (10,000,000 seedlings) lọdọọdun, awọn yio si ma a lẹ to iye na ni ọdun kọọkan ti o ba ntẹle ara won.

Oloye Dẹkọ tun sọ pe, Ijọba ti fi ọgọrun-ọkẹ ponun (2,000,000) silẹ fun lilẹ ati gbingbin awọn eso-koko na ni Ipinlẹ Iwọ-Orun yio si tun ya awọn agbẹ ni ọkẹ-mejilelọgọta ọ le ẹgbaa.

Wo oju ewe kẹwa

## Akintọla gba Billy Graham Ajihinrere lalejo

IBADAN.

LEHIN ti Dọkita Billy Graham, Olokiki Ajihinrere ara Amẹrika ti pari iṣẹ iwasu rẹ tan l'Eko ni o ba kọja lọ si Ibadan pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ ni ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ kini oṣu yi. Nigbati Ajihinrere na si de Ibadan ni Oloye S. L. Akintola, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun si pe ase apejẹ fun un ni Ile Itaja Onjẹ "Lafia Rest House" Ibadan,



Aworan ti oke yi ni ti igbati Dokita Billy Graham Ajihinrere nwasu fun awọn enia gbalansa ọdan ni Ibadan, Nibẹ na ni Oloye S. L. Akintọla Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun gbe nsọrọ sinu ẹrọ gbohun-gbohun fi ki Ajihinrere olokiki na ku abọ

## Awọn Ẹgbẹ Olomi da Ọga mẹta duro nibi iṣẹ nitori Idibo

[illegible]

## Adajọ sọ ẹniti o nfẹ jale sẹwọn oṣu mẹfa

EKO

[illegible]


### AKIYESI FUN ONKAWE

Eyi ni lati sọ fun nyin pe, ẹnikẹni ninu ẹnyin onkawe ti o nkọwe si Olotu Iwe Irohin Yoruba ti ko ba fẹ ki iwe on sọnu ki o maa kọ ọ taara si ile iṣẹ rẹ ni :

Amalgamated Press Ltd.,
5/7, Apọngbọn Street,
P. O. Box 163, Lagos.



**Nihin ni IRORA rẹ wa**

*Iwe aworan yi ni o fi ibiti aisan gbe wa lara han nigbati awọn erce inu rẹ ko ba ṣiṣẹ deede*

**DeWitt's**

**Kidney & Bladder Pills**

nṣe iṣẹ atunṣe erce inu taara ni lati ti oro inu ti o ngmu irora wa jade

LAKUREGBE, ARA-RIRO, EHIN-DIDUN ATI GBOGBO IYỌNU APO-ITỌ DURO



**DeWitt's**

**Kidney & Bladder Pills**


# ADIGUN LỌ BẸ IṢẸYIN WO



Eyi ni aworan Ọlọla J. Ọla. Adigun, Minista Alamojuto eto iṣẹ Ilera ati Alafia nigbati Ọgbẹni Ogunjimi, Ọga ẹka ile iṣẹ Iwosan 'Baptist' nfi tabili ti nwọn fi ngbe alaisan han an ni Shaki. Dọkita E. P. Dosher ti o nṣe itọju awọn alaisan ni wa lẹhin.



Aworan yi ni ti Ọlọla J. Ọla. Adigun, Minista Alamoju o eto iṣẹ Ilera ati Alafia nigbati o mba awọn Igbimọ Ilera ti Ijọba Ibilẹ Iṣẹyin sọrọ ni Iṣẹyin. Ọlọla na ni o joko si aarin wọn ti o de fila funfun.



Dọkita T. O. Lambo, Ọjọgbọn Oniṣegun ti Ile-Itọju awọn alaisan-ayiri Aro, Abẹokuta wa ni itọju rẹ ni o wọ ṣokoto kukuru ti nṣe alaye aisan fun awọn Ikọ ilu Yugoslav ti o wa bẹ ibẹ wo.


**Ẹ MA KA IWE IROHIN YORUBA**




Aworan Ọgbẹni M. A. Ọlawaji, Minista Alamojuto eto Ilu niyi, nigbati o nsọrọ ni ibiti nwọn gbe nfi ipilẹ Ile-iwe iṣẹ agbẹ ati iwadi ohun ọgbin [Agriculture and Agricultural Research Laboratories] ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun lẹlẹ ni ile-iṣẹ agbẹ (Moor Plantation]

# AWORAN ONITAN



# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

## Adajọ sọ awọn onijagboro mẹfa sẹwọn

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ keta oṣu yi ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ Ihima sọ awọn ọdaran mẹfa, Seidi Omuyi, Abdul Sadiku Ozigi, Abdul Raimi Aiyebisi, Moru Omọde, Seibu Oyibo ati Ozobeke sẹwọn oṣu mẹfa-mẹfa pẹlu 'ibodi' ẹgba mẹfa mẹfa nitoripe nwọn jẹbi ẹjọ ijaigboro ti awọn ọlọpa ba awọn marundinladọta se. Ni abule Ogborke, larin ẹgbẹ oṣulu meji ni ọjọ kẹjọ oṣu kini ọdun yi ti ijaigboro na bẹsilẹ.

Adajọ na ni ki awọn mẹta kan ninu wọn lọ fi pọnun marun-marun tanran, ki awọn mẹrin miran si lọ fi ponun meji meji tanran, o si da awon mejilelọgbọn yoku silẹ o ni nwọn ko jẹbi. O le ni ọjọ mọkanla ti nwọn fi ṣe ẹjọ na o si fẹrẹ to awon enia mẹjọ ti nwọn wa jẹri nipa ọran na.

## Onigbajamọ kan pokunso

JOS.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrindilọgbọn oṣu ti o kọja yi ni onigbajamọ kan, Timothy Chima, ẹni ọdun mejidilọgbọn, pokunso ti o si pa ara rẹ sinu ile ti o ngbe ni 29/12, Bwzu Street, Jos.

Awọn ara ile rẹ ni, ni ale ọjọ Aje ki nkan yi to ṣẹlẹ, ọkunrin na tete wọle sun, ṣugbọn nigbati o di owurọ ọjọ keji ti iṣe ọjọ Iṣẹgun ti awọn ara ile na fura si alaikotete jade sode ọkunrin yi, ni nwọn ba fi agbara ṣi ilẹkun yara rẹ wọle ti nwọn si ri i nibiti o gbe fi okun so ara rẹ si ti o si ngmi doro-doro. Awọn ọlọpa si gbe oku re lọ sile awọn lakulaku fun ayẹwo.

# Awọn Ọlọja binu kọ iṣọ silẹ nitori Ọlọfa Titun

ỌFFA.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejidilọgbọn oṣu ti o kọja yi ni awọn ọlọja ti o ni awọn iṣọ ọja ti Ijọba Ibilẹ Offa fi ẹgbaa mẹtala pọnun (£26,000) kọ fun wọn ṣe ipinnu lati kuro ni iṣọ wọn, nwọn si fi ibinu kuro loja na lati fi ibinu wọn han pe awọn ko faramọ Malam Mustapha Keji gẹgẹbi Ọlọfa titun ti awọn Alaṣẹ Ijọba Ibilẹ Ilọrin yan fun wọn dipo Ọba Wuraọla Isloye ti nwọn wa kuro ni Ekun Ilọrin.

Oniruru iwa ko-tẹ- wa lorun ati ifi-ibinu han ni awọn ara ilu Ọffa ti fihan pe awọn ko faramọ fifijoye ti nwọn fi Malam Mustapha Wuraọla Isloye Ọlọfa Ọffa ti nwọn wa kuro ni ilu Ọffa na.

## Enia meji ku sinu ṣalanga ni Jos

JOS.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu ti o kọja yi ni awọn lebira meji, Aposa Miango ati Danbaba jin sinu salanga kan nibiti nwọn gbe ngbẹ ṣalanga tuntun kan lọwọ, nwọn si ku sibẹ lẹsẹkẹsẹ. Lebira ti o si kẹta wọn Chindu Miango fi ara pa nibiti o gbe nduna pe ki on na ma jin sibẹ, nwọn si gbe e lọ si Ile-iwosan fun itọju.

Ni ọjọ ti ijamba yi ṣẹlẹ, awọn lebira ile iṣe imọtoto yi ngbẹ ṣalanga tuntun kan lọwọ nibiti awọn agbepoo yio gbe ma a da igbẹ si, nwọn ko si mọ pe leti bebe eyiti nwọn ti dilẹ rẹ ni awọn gbe nwa, nibiti nwọn gbe ngbẹ titun yi lọwọ ni iyẹpẹ ti atijọ ba jin sinu ti o bo enia meji mọlẹ ninu wọn, ni ijọ kanna ni nwọn si ti sinku wọn.

## Adajọ sọ iṣanṣa kan sẹwọn oṣu mẹsan

KADUNA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ Kaduna sọ ọdaran kan Ibrahim Usuman ti awọn ọlọpa pe ni 'ọrẹ wa' sẹwọn oṣu mẹsan nitoriti o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọja ba a ṣe pe ole ati isansa ni.

Ejọ ti awọn ọlọpa asode ro fun Adajọ ni pe nwọn ri ọdaran na ni ọganjọ oru ọjọ kan ti o nrin kakiri Adugbo Kano, nigbati ọlọpa na si bi i lere pe kini o nwa kakiri, ko le fi esi pataki kan.

Ọdaran na si sọ fun Adajọ pe, on 'ṣẹṣẹ mbọ'' lati Zaria ni, on ko si mọ ibiti on yio gbe, ni Adajọ ba fi sọ ọ sẹwọn.

## *Ẹniti o gba ọlọpa loju fi £5 tanran*

KADUNA.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kọkandilọgbọn oṣu ti o kọja yi ni Adajọ Adapọ Kotu Ijọba Ibilẹ Kaduna ṣe idajọ pe ki ọdọmọde 'birin kan, Jamai fi ponun marun (£5) tanran si kotu tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu kan nitori ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun pe, o gba ọlọpa Apapọ Ijọba Naijiria kan loju.

Ki Oluwa jẹki ọmọ rere gbẹhin gbogbo awọn alabaṣẹyẹ. Amin.

## Okesọla komọjade

KADUNA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni Ogbẹni Latifu Okesọla ṣe ikomọjade ọmọ ti Oluwa fi ta on ati iyawo rẹ lọre, Iyaafin Wulemọtu Adukẹ lọrẹ, nwọn si sọ ọmọ na ni Muhamed Taofiki. Baba ọmọ na si fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun.

Awọn diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn ti o wa si ibi aṣẹyẹ ikomọ na ni Ọgbẹni Amusa Iyanda, Bello,, Alimi, Sikiru Mọmọdu, Yisa, Lasisi Jolaiya, Iyaafin Fatumọ Alakẹ, Aṣlawu Ṣifawu ati Raliatu.

Ire a kari o.

## Ijọba Ghana fẹ ṣe ofin ẹwọn gbere lori owo Aiyederu

ACCRA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdogbọn oṣu ti o kọja yi ni Dọkita Kwame Nkumah, Alakoso Ijọba Ghana, ṣe ikede nigbati o mba awọn Oloye kan sọrọ ni ibi ipade kan ti nwọn ṣe ni Dunkwa, pe Ijọba awon nṣe eto lọwọ lati gbe ofin kan jade nipa awọn ti nwọn nfẹ ma a rọ owo aiyederu.

Dọkita Nkrumah ni nigbati ofin yi ba jadẹ ẹwọngbere ni awọn yio ma a ju awọn ti o ba ro owo-aiyederu na si, ni ọgba-ẹwọn si ni iru ẹnibẹẹ yio si wa ti yio ma a na owo ti o rọ na. Awọn ọlọpa Ghana si wa lẹnu iwadi awọn ti nwọn fura si pe nwọn ntẹ owo beba Ghana- lọwọ nisisiyi.

## Ijamba bọọsi pa awọn enia meji

ENUGU.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ogbọnjọ oṣu ti o kọja yi ni ijamba mọto bọọsi nla (Volkswagon bus) kan pa Ọgbẹni kan ti o ngun basikulu ati ọmọ ọdun marun kan ti o gbe gun un ni ọna Enugu si Onitsha, nigbati bọọsi na ṣeṣi kọlu wọn. Lẹsẹkanna ni ẹniti o ngun basikulu na ku, ọmọ na ti o si gbe gun un ku si Ile-iwosan ni ikẹhin.








Aworan oke yi ni ti igbati Ọgbẹni J. W. G. Tilly, Alakoso kan ninu iṣẹ awọn Ẹgbẹ Ọlọkọ "Palm Line" mba Ọba Ilọrin, Malam Sule Gambari sọrọ ninu ọkọ "Ilọrin Palm" ti nwọn fi orukọ ilu rẹ sọ ọkọ na ti o gnnlẹ si ebute ọkọ Eko ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ karun oṣu yi, ọkọ "Ilọrin Palm" na jẹ ọkọ elefin kẹwa ti awọn Ẹgbẹ Ọlọkọ na ran wa si Iwọ-Orun Ilẹ Enia-dudu.



Awọn ogunlọgọ enia ti o wa gbọ ọrọ Billy Graham Ajihinrere ni gbangba-ọdan Ibadan.


# Fi Warakaṣi Kraft pese onjẹ daradara kiakia

O dara lori buredi tabi akara-oyinbo




Warakasi KRAFT dun lenu o si nyo enia to bee gee. O ya lati fi pese onje kiakia pelu irorun fun gbogbo ebi! Enikeni feran re. Fi si ori buredi tabi akara-oyinbo fun awon omode nigbakigba ti ebi ba npa won. Bere fun Warakasi Kraft ni Ile-itaja. Wa a ri i pelu irorun ninu agolo oniruru ati yelo.

**KRAFT** Kraft Foods Limited, Regina House, Marylebone Road, London, N. W. 1


# Ariyọ jalaisi

EKO.

NI alẹ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni Ọgbẹni Sulaiman Alabi Ariyọ ọga Atukọ (Captain) Marine ku si ile rẹ ni 54 Docemo Street, l'Eko, nigbati o di eni ọdun mokandinladota, lẹhinti o si ti ṣe aisan fun ọjọ meji.

Awọn atukọ 'Marine Department' ibiti ologbe na gbe nṣiṣẹ ni igba-aiye rẹ ni nwọn wa fi moto wọn gbe oku rẹ lati ile rẹ ni deede agogo mẹrin irọlẹ ọjọ keji ti o ku lọ si itẹ-oku Ikoyi nibiti nwọn gbe sin in si. Imam-Agba Liadi Ibrahim ni o ṣe isin ikẹhin fun un.

Awọn Alhaji, Alfa, Lọya, Dokita ati gbajumọ ni nwọn pe ṣoṣọ si ibi isinku rẹ na. Nigbati nwọn ngbe e lọ sin, ọpọlọpọ wọn ni nwọn nsunkun, paapa aya ologbe na, awọn ẹbi rẹ ati Lọya K. K. Arẹmu Kọtun, orẹ imulẹ ologbe na.

Ọmọ-ọmọ gbajumọ ati olowo ologbe Ariyọ 'Mekudi' ti Kọta Ariyọ (Upper Offin Lane) l'Eko ni ologbe Sulaiman. Ile-iwe Ereko Methodist ati King's College l'Eko ni ologbe na gbe kowe dada ki o to lọ siṣẹ atuko ni ọgba ile-iṣẹ Marine l'Apapa ninu ọdun 1933. O le siṣẹ pupọ na, on si ni ọmọ Naijiria ti o kọkọ de aye ọga iṣẹ (Assistant Chief Harbour Master) o fẹran lati ma a ṣe ẹtọ ati ododo, o ni oyaya, gbajumọ ni i, o si lawọ pupọ nigba-aiye rẹ. O fi ọmọ marun si aiye lọ.

Ki Ọlọrun pa ẹṣẹ rẹ rẹ ki O si tun ẹhin rẹ ṣe.



Ologbe Sulaiman Alabi Ariyọ

Printed and published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd., 5/7, Apongbon Street, Lagos (Editorial) and Advertisement Office) Telphone 23675, 23676. Fun owo "Irohin Yoruba" odun kan, Eko sile mejo ati kobo mejo (8/8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile metala (13s.) Olotu B. M. ADEMUYIWA, 2 Idumagbo Street Idi-Oro